**LAKAYE ỌRỌ**

Ẹniti oye ku fun a ma a gan Ọmọnikeji rẹ, ṣugbọn ẹni oye a pa enu rẹ mọ. Alayidayida enia da ija silẹ; asọrọ kẹlẹ ya awọn ọrẹ nipa.

# IROHIN IMỌLẸ

MOTTO: IMỌLẸ DE, OKUNKUN PARADA.

**OWE**

Bi owe bi owe ni a nlu ilu Agidigbo, Ọlọgbọn ni njo o, Ọmọran ni mọ ọ, Nitoripe ewe koko ni nwọn fi ṣe awọn rẹ, igi ganmuganmu ni nwọn fi nlu u bẹni ko gbọdọ faya ko si gbọdọ ma dun.

VOL. VI No. 347 MONDAY SEPTEMBER 10 — SEPTEMBER 16 1962 KỌBỌ MEJI (2d)

# ARỌ KAN GBA ONJẸ LẸNU AFỌJU

IBINNI:- Gbogbo kotu lo kun sosọ ni ọjọ Ọjọbọ ti iṣe ọjọ kefa oṣu yi nigbati awọn Ọlọpa mu Ọdaran Arọ kan, Ikopmwon Nojeru wa siwaju Adajọ kotu Ijọba Ibilẹ Ibinni, fun esun pe, o gba onjẹ lẹnu afọju.

Ọlọpa ti o mu Ọdaran Arọ na ṣe alaye fun kotu pe, nigbati Afọju kan, Obe Odoise ra ẹba nitoripe ebi npa a, o si joko njẹun rẹ ẹhin lẹhin gbongan ti awọn npe ni "Conference Hall"

Bi o si ti njẹun lọwọ, ti Ọdaran na ri i, lẹsẹkẹsẹ ni Ọdaran Arọ yi ba gbe panu onjẹ na niwaju Afọju ti o si joko ti onje na o si njẹ ẹ.

Bi Afọju na ti fẹ bu onjẹ, ile ni o fi ọwọ gun, ni o ba bẹrẹsi wa panu onje rẹ, bi o si ti fi ọwọ onje ti o njẹ kan Arọ na, ni Ọdaran Arọ na ba bẹrẹsi fi pọpa rẹ lu Afọju, o tun da ọgbẹ si i lara. O si tun jẹ onjẹ Afọju na tan patapata.

Adajọ paṣẹ pe, ki nwọn o fi Ọdaran Arọ na pamọ si ọgba ẹwọn fun ayewo awọn Dokita ki awọn Olopa o si mu u wa si kotu ni ọjọ kẹsan oṣu ti mbọ.

## Awọn Ọlọpa ri ori enia marundinlogoji ninu ile ọkunrin kan

Ẹniti o se ohun ti ẹnikan ko ṣeri, oju rẹ a ri ohun ti ẹnikan ko ri ri. Ọjọ nla ni ọjọ na, nigbati awọn Ọlọpa bẹrẹsi ko ori ọmọ enia jade ninu ile Oloye kan, Agbaragba ni agbegbe Ikom, ni ọjọ Iṣẹgun ti iṣe ọjọ kerin oṣu yi.

Ọgbẹni E. D. Sigalo, ti iṣe Ajẹlẹ agbegbe na ni o ranṣẹ si awọn Ọlọpa pe, pipa ti awọn enia kan bẹrẹsi pa enia kaakiri ti pọju nisisiyi ti o jẹ wipe o fẹrẹ jẹ pe ojojumọ ni enia nsọnu ni agbegbe na.

Lẹsẹkẹsẹ ti awọn Ọtẹlẹmuyẹ ri iwe Ọgbẹni Sigalo gba ni nwọn ba gbera. Nigbati nwọn wọ ile Oloye wọn, ori enia marundinlogoji ni nwọn gbe jade ninu ile Oloye na.

Awọn Ọlọpa ti gbe awọn ori enia na lọ si ile-iṣẹ awari ohun ijinlẹ ni Oshodi boya nwọn sẹṣẹ pa wọn ni tabi nwọn ti pawọn tipẹ.

## Adẹtẹ kan wẹwọn oṣu mẹfa

Ni ọjọ'Ru ti iṣe ọjọ karun oṣu yi ni Adajọ kotu Apapọ Kano ṣe idajọ pe, ki Ọdaran Adẹtẹ kan, Audu Katsina lọ si ẹwọn oṣu mẹfa nitoripe o jẹbi ẹsun ti awọn Ọlọpa fi sun un.

Ọlọpa ti o ba Ọdaran Adẹtẹ na sẹjọ ṣe alaye niwaju Adajọ na pe, nigbati awọn ole fọ ile kan ti awọn onile na si wa sọ fun awọn, awọn lọ si ile na lati lọ wo o. Lẹsẹkẹsẹ ni awọn si bẹrẹsi wa awọn nkan ti awọn ole na ko ninu ile, ni awọn ba ri ẹru na lọwọ Ọdaran Adẹtẹ na.

Ọdaran Adẹtẹ na gba pe on jẹbi, ni Adajọ ba ni ki o lọ fi ẹwọn oṣu mẹfa jura.

ADVT. No. 151

**Ṣe o ti lọ parọ owo atijọ ọwọ rẹ si OWO TITUN**

TI ILẸ NAIJIRIA?

O le parọ owo pepa korensi l'ọfẹ titi di ipari oṣu SEPTEMBER ti a wa ninu rẹ yi.

*Ti owo ṣile ati awọn owo wẹwẹ di ipari oṣu DECEMBER*

## ỌMỌGE TI KO L'ỌKỌ KINI O FI LOGBA A ?



Ọmọge [illegible] ti o sṣẹ de lati ilu Oyinbo, ti a nwo aworan rẹ ninu iwe yi je ọkan ninu awọn ọmọ jaiyejaiye ode isisiyi. Ka iwe Irohin Imọlẹ ọsẹ ti mbọ, ki o gbọ ohun ti o fẹ sọ.

# ỌRỌ OLOTU

## IJỌBA, Ẹ MOJU TO ỌRỌ YI

OHUN ti o fa akọle ọrọ wa ọsẹ yi ni aghosọgbanu irohin ti awọn ọmọ ilẹ Naijiria ti nwọn wa ni ilu Oyinbo ti awọn lọ fun ẹkọ.

Oniruru irohin ni a ngbọ nipa awọn ọmọ na nigbogbo igba wipe, "Ori wọn ndaru nigbati nwọn ba de ilu Oyinbo" Ni ọdun ti o koja, yi enia merinlelogorun (104) ni ori wọn daru ti nwọn ko si mọ ohun ti nwọn nṣe mọ.

Lẹsẹkẹsẹ ni Ijọba Iwọ-Orun Naijiria ran Dọkita T. A. Lambo lọ si ilu Oyinbo lati lọ wo awọn ọmọ wọnyi, ati pe kini ohun ti awọn le ṣe ti iru rẹ ko fi ni ṣẹlẹ si awọn ọmọ wa mọ. Iwadi yi ki i iṣe ekini ti awọn ọjọgbọn Dọkita yio ṣe.

Ni ọdun kẹfa sẹhin nisisiyi ni Ijọba ran Dọkita na lọ lati lọ ṣe iwadi ọrọ yi. Nigbati o si pada de lati ilu Oyinbo o tẹ awọn awari rẹ jade fun awọn Ijọba Naijiria lati gbeeyewo.

Lati igbana, awọn Ijọba wa ko ṣe nkan lati ri wipe, gbogbo awọn awari Dokita na jẹ eyi ti nwọn gba ti nwọn si tun ṣe wọn. Ki nwọn si mojuto ohun ti o nmu ori awọn ọmọ wa yi daru ni ilu Oyinbo. Bẹni arun yi ko si dinku.

Ni ojojumọ ni awa oniwe Irohin Imọle ngbọ irohin wipe nkan tun npọ si i ni, ko si dinku rara. Inu wa yio dun ti awọn Ijọba wa ba le ba wa mojuto ọrọ yi, ki nwọn o si ṣe gbogbo nkan ti Dokita Lambo sọ wipe o nmu awọn nkan wọnyi wa.

Awa oniwe Irohin Imọlẹ ri i pe akoko to nisisiyi lati ri wipe gbogbo awọn ti o wa nidi eto na tete ṣe awọn nkan na ni akoko ki o ma si ṣe pẹju bi o ti yẹ lọ.

Ko si inu Obi ti yio dun nigbati o ba gbọ wipe ori ọmọ on daru nigbati o de ilu Oyinbo, bẹni eyi ko si tun ni fun orilẹ ede wa ni orukọ rere. Nitorina, awa oniwe Irohin Imọlẹ bẹ ẹnyin Ijọba wa ki ẹ tete moju to ọrọ yi.

# YẸYẸNATU!

## Oni yẹyẹ Eko

Olotu:— Yẹyẹnatu, pe bawo ?
Yẹyẹnatu:— Pe bakanna ni kẹ
Olotu:— Haba! ẹ ma nrọ kẹ.
Yẹyẹnatu:— Kini mo rọ fun, o nbi yin mou ni ? Ẹtanu ko ma raja Kinswe
Olotu:— O le ra a kẹ
Yẹyẹnatu:— To ba ra a, ko le gbe wale To ba si gbe wale ko le lo o.
Olotu:— Ko le win Miss Legos paapa
Yẹyẹnatu:— Kini ? Ṣe ẹtanu ?
Olotu:— Yẹs! o ri fọto ẹniti nbinu pe nwọn kó mu on ni Miss Legọs ni ?



Yẹyẹnatu:— Ha! ṣobinrin to wọ pata yẹn ?
Olotu:— Yẹs.
Yẹyẹnatu:— O dara kẹ. Ẹnyin ko laiki rẹ ni ?
Olotu:— Nonsensi ni yen kẹ.
Yẹyẹnatu:— Ṣe ntoripe o wa ni ihoriho ? Ṣebi ẹ ni ilaju ni yẹn
Olotu:— Iyẹn ti poju
Yẹyẹnatu:— Ẹ ko mọ pe o lọ silu oyinbo ṣa ?
Olotu:— Nigbana nkọ ?
Yẹyẹnatu:— O wa ni ankọ kẹ Tabi ẹ ko mọ
Olotu:— Mọ kini ?
Yẹyẹnatu:— Okini wẹwẹ ni kẹ
Olotu:— Tani o wa nmu nigan ?
Yẹyẹnatu:— Ẹ jọwọ sa, awọn wo ni mo fi mu yin ?
Olotu:— Hẹ! ara okan ta fi nsọ pe o laju na ni yẹn. O ngbaṣa fun mi.
Yẹyẹnatu:— Sọri o, boya ti nba mura bi ẹni wa niwaju iwe Irohin yin ṣa, ngo laju
Olotu:— Ẹjọ rẹ ni
Yẹyẹnatu:— Bọti ṣa, loju temi o dabi ẹnipe awọn obinrin laju nilẹ yi ju ọkunrin
Olotu: Wayi, rara o.
Yẹyẹnatu:— Haba! hẹ! ẹtanu ni yi ẹ fara bagraund kẹ
Olotu:— O dara bawo ?
Yẹyẹnatu:— In di fọs ples obinrin nwọ sokoto kakiri ni ẹni taimu. Kini ṣe tao ri ọkunrin ko wọ kaba kiri ?
Olotu:— Hun! hun ṣe o tan ?
Yẹyẹnatu:— Tan kẹ. Horaiti, ekeji. Awọn obinrin to laju dadadara ihoriho ni nwọn nrin, kini ṣe ti ko si ọkunrin ti o nrin ihoriho ?
Olotu:— Ni temi, emi ko le rin ihoriho
Yẹyẹnatu:— Nitori kini, nitoripe ẹ ko laju
Olotu:— No kẹ, nitori nko ṣiwere
Yẹyẹnatu:— Ha-hẹn! ẹ min pe were lo nrin ihoriho ?
Olotu:— Wẹll, o le jẹ bẹ
Yẹyẹnatu:— Ṣebi ẹ si nfẹ ki ẹ ma mura bẹ
Olotu:— Rara, Adija ni mo fẹ ko mura bẹ.
Yẹyẹnatu:— Nitori kini ?
Olotu:— Mo kan fẹ bẹ ṣa
Yẹyẹnatu:— Ha-hẹn! ṣe ntoripe ko juwọ silẹ ?
Olotu:— Mo kan laiki ẹ ni. Ṣebi mo sọ fun rẹ ?
Yẹyẹnatu:— Ha! ẹ ma forẹ mi tọba. O dabọ o.

---

Anu ṣe gbogbo enia nigbati ọkunrin kan, Savage fẹ wọ ọkọ ojuomi ti ọwọ rẹ seesi yẹ o si ko sinu odo ọsa. Awọn Ọlọpa ko ti ri oku ọkunrin na. Nigbati nwọn nwa, ni nwọn ba ri oku ọmọ'ọdun mẹrin kan Wahabi Olu ti o ngbe Tokunbọ l'Eko.

# Limọta Oluwa ṣe igbeyawo ọmọ-ọmọ rẹ

EKO:- Irohin ko to afojuba ni ti inawo igbeyawo ti Limọta Oluwa: ẹniti a mọ adape orukọ rẹ ni Iya Agbekẹ ti Iya-Afin Ọmọ-ọba Adeniran Adefarakan, ṣe fun ọmọ-ọmọ rẹ Sidikatu Ayẹni, ni opopo Idi-ọmọ, Isalẹ Eko, ni ọjọ Aiku ti iṣe ọjọ keji oṣu yi.

A so yigi Sidikatu fun Ọgbẹni Buraimọ Akanni larin ogun-lọgọ Alfa, Alhaji Alhaja ati aimọye Sanmọri ilu Eko, ni deede agogo mẹwa owurọ.

Lẹhin ti a so yigi tan, ni Iya-afin Limọta Oluwa (Iya-Iya-Iyawo) ti bẹrẹsi fi onjẹ adidun tun awọn ẹgbẹ ati ojulumọ rẹ lẹnu ṣe, ti awọn na si wa ni yọtọmi titi ilẹ ọjọ na fi ṣu, bakanna ni Alagba ti a mọ adape orukọ rẹ ni "Guard Ayẹni" ti iṣe Baba-baba Iyawo, fi ile pọn ọti, to tun fi ọna ro ọka, tiʃawọn ẹgbẹ rẹ nfi igbadun ṣayọ.

A ko tun le f'ẹnu sọ ti Silifata Ọmọshalewe (Iya-Iyawo) Irohin aṣeyẹ ọjọ na ko to afojuba, ẹni ti o ba de ibẹ, lo le sọ. Oriki ti "Irohin Imọlẹ" le fun Iyawo na ni:- "A bi ibi ṣuṣu bi ewe igba, a bi ara jojo bi ewe ẹmi"

Ki ire ko kari gbogbo wa o.

---

## ONIJIBITI KAN FI (£50) TANRAN

OSHOGBO:- Gbogbo Kotu lo kun ṣoṣọ ni ọjọ Iṣẹgun ti iṣe ọjọ kẹrinla oṣu yi nigbati awọn Ọlọpa mu Ogbokangi Onijibiti kan, Raimi Bello ẹni ọdun marundilogoji wa siwaju Adajọ kotu Ijọba Ibilẹ, Oshogbo fun ẹṣun jibiti.

Ọlọpa ti o ba ọdaran na ṣejọ ṣe alaye fun kotu wipe, ọdaran na pe ara rẹ ni asoju awọn Alapata ẹran ewurẹ ati malu, o si sọ fun awọn enia wipe awọn yio gba enia lati ma a ṣiṣẹ labẹ on.

Nigbati awọn enia gbọ bayi, nwọn nlọ si ọdọ re lati ṣiṣẹ. O si gba ponun mejilelogbọn ati ṣile merindinlogun (£32 : 16) lọwọ enia merin Omidan Felicia Oyelude, Florence Ọsho, Ọmọlayan Afọlabi ati Elizabeth Fayọyinwa.

Ọlọpa na tun sọ fun kotu wipe, nigbati ọdaran na ti gba owo lọwọ awọn ọmọ na ni oṣu kẹta ọdun yi, ni ko ti wi nkankan fun awọn ọmọ na mọ ju wipe, "Wa loni, ẹ wa lọla" bẹni ko si da owo wọn pada mọ.

Nigbati ọdaran na rojọ ti o si gba wipe on jẹbi, ni adajọ ba ni ki o lọ fi adọta ponun (£50) tanran si kotu tabi ki o lọ si ẹwọn oṣu mẹfa lafarabara.

# Jesu Kristi ni Olugbala wa

*Lati Qwọ:— ASIWAJU PAUL AGBOOLA OLADIPO*

Li ọsẹ ti o kọja, a fi awọn asọtẹlẹ rẹ han wa lati ẹnu awọn Woli, ṣugbọn yio dara lọpọlọpọ bi a ba le fi han wa nipa ọrọ rẹ ati agbara, ati ohun ti iwe Mimọ wi nipa Jesu Kristi.



Ọna pupọ ni Iwe Mimọ ti wi nipa Jesu Kristi ti o si pe e ni Olugbala, lẹhin rẹ ko si t u n si Olugbala miran mọ nitori iku rẹ lori agbelebu fun ẹṣẹ temi ati iwọ. Bakanna si ni gbogbo ijiya rẹ. Bi awọn ijiya na ti ṣe lọ ẹo ma a gbọ ni ọsẹ to mbọ.

Awọn ẹri ti o fi han wipe Jesu ni Olugbala ni wọnyi:- Jesu sọ wipe, "Emi ko wa lati ṣe idajọ aiye, bi kọṣe lati gba aiye la" Johanu 12 : 47 Jesu ni Emi ni ọna ati otitọ, ko si ẹniti o le wa sọdọ Baba bi ko ṣe nipasẹ mi" Johannu 14:12. Ko si igbala lọdọ ẹlomiran nitori ko si Orukọ kan labẹ Ọrun ti a fi fun ni ninu enia nipa eyi ti a le fi gba wa la A. C. T. 4·12. Gba Jesu Kristi gbọ ao si gba ọ la, iwọ ati awọn ara ile rẹ pẹlu A C.T. 12 ; 8 de 31 nitori awa tikalara wa ti g b ọ ọrọ rẹ awa si mọ pe nitotọ, eyi ni Kristi na Olugbala araiye Johannu *4: 42* Anu ati alafia lati ọdọ Ọlọrun baba wa ati Kristi Jesu Olugbala wa Titu 1: 4 ati ti Olugba la wa Titu 2: 13.

Li o da wa si lori Ọpọlọpọ nipasẹ Jesu Kristi Olugbala wa Titu 3: 6 Bi o ti sọ di pipe o wa di orisun igbala ainipẹkun fun gbogbo awọn ti o gbọ ti rẹ Heberu 5: 9.

Iwe awọn ẹnikeji wa sọ bayi wipe awọn ti wọn gba Jesu gbọ, ao gbe wọn ga ju awọn ti ko gbaa gbọ lọ ati awọn ti ko gbaa gbọ laiye kan to mbọ. Ki yio si Olusanlọwọ f u n wọn. Alukurani Surat 3 ayat 54 de 56.

Ara n i u u Oluwa, ko si ariyanjiyan kan nipa igbala Jesu. bi o ba ṣe ifẹ rẹ ati Ọlọrun o ti daju wipe Alujanna ni ile mi ati iwọ. Bi ẹnikan ko ba gbagbọ ati de ọdọ Ọlọrun, yio soro fun onitọhun yẹn.

Iwọ ha m u r a tan lati gba a bi ? ki o si ṣe igbagbọ bẹbẹ ti ko ba ṣee gba tara. O ti daju wipe emi ko ni fi ẹlẹṣin silẹ ki nba ẹlẹṣẹ lọ.

Jesu wi fun ole owọ ọtun rẹ wipe loni ni iwọ yio wa pẹlu mi ni paradise.

Alafia Ọlọrun ati Ore-Ọfẹ lati Ọdọ Jesu Kristi Olugbala wa ki o wa p ẹ l u Olukuluku nyin.

# A B D Olowe

*Lati Ọwọ:- ẸBUN MODUPẸ*

A. Agbẹjẹ gba wọn la t a n, nwọn ni ki a pa a ni panṣa
B. Bi Ọlode ko ku, ode rẹ ki hu gbẹgi.
D. Dẹngẹ tutu lẹhin, ẹgbona ninu.
E. Ebi ko pa Imale, o ni on ki jẹ aja, ebi pa Sule o j'ọbọ.
Ẹ. Ẹniti o fẹ arẹwa fẹ iyonu, ẹni gbogbo ni iba wọn tan.
F. Firi n'idi ọkẹ, a lọ k'olohun digbe.
G. Giri lẹhin asọdodo, akọ maa t'osika lẹhin.
GB. Gbolohun k a n ba ọrọ jẹ, gbolohun kan tun ọrọ ṣe.
H. Hamha ni ọpọlọ fi ga ju alamẹ lọ.
I. Ilara alaju ni mu wọn gba jẹ, ni mu wọn ṣeso.
J. Yoyọ Agbo ni i mu Agbo niyi Ọla baba ni mu ọmọ yan.
K. Ko si ẹniti nṣika ti Ọlọrun ko ni da lẹjọ
L. Lakaslaka ko ṣe fi faja, ọmọ ẹ-rgun ko ṣe fi ṣe ọmọ Iyawo.
M. Malu ti ko ni i r u, Oluwa ni i ba l'ẹsinsin.
N. Nwọn ni, Amukun, ẹru ṣe wọ" o ni "Lati ilẹ lo ti wọ wa"
O. Ojo owuro ti i bi olowo ninu Olowo gẹlẹtẹ Iwọfa gẹlẹtẹ.
Ọ. Ọrọ pupọ ki kun agbọn.
P. Pipẹ ni yio pẹ, akololo yio pe baba.
R. Riro ni ti e n i a, ṣiṣe ni ti Ọlọrun.
S. Sisunmọ ni, ni a nmọ iṣe ẹni, enia gbe okere niyi.
Ṣ. Ṣokoto ti nṣẹ aran ko bọ oko.
T. Tẹtẹrẹgun ti l'omi tele ki ojo to de.
W. Were d u n wo, ko ṣe bi l'ọmọ
Y. Yinniyinni ni i ni k'ẹni ṣe mi.

# FEYI KOGBỌN

*Lati ọwọ:— S. A. FATOLU* IBADAN.

A GBA LOWO MERI

Ni ọjọ kan ọkunrin kan wa ni ilu Eko, ti o pinnu lati tan gbogbo enia jẹ.

Ọkunrin yi dide ni ọ j ọ kan, o bẹrẹ si purọ pe Oyinbo fẹ da iṣẹ kan silẹ, on ni nwọn yan fi jẹ Ọga nibi iṣẹ na. Ẹniti o ba fẹ iṣẹ ki o tọ on wa, on yio si fi si ibiṣẹ na. Nipa ṣiṣe eyi o bẹrẹsi gba ọpọlọpọ owo lọwọ awọn enia; bi ẹnikan ba wa si ọdọ rẹ pe on fẹ ṣiṣẹ, a wi fun pe ki o lọ mu ponun mẹta (£3) wa on yio si fi jẹ ọga lori ọgọrun enia ti o ti gba.

Bi ẹlomiran ba de a sọ fun un pe ki o lọ mu ponun marun (£5) wa on yio si fi jẹ ọga lori igba enia ti on yio gba laipẹ yi. Bi awọn enia ti gbọ pe nwọn ti da iṣẹ kan silẹ, tẹni nwọn nwa ti ọkunrin yi si ngba owo lọwọ olukaluku wọn.

Ọkunrin yi gba to ẹgbẹfa enia, o si ko ada fun wọn. pe ki nwọn ma a ge koriko Awọn eyini gba ada, nwọn si nge koriko. Nigbati awọn ti o nta onjẹ ri wọn, nwọn bẹrẹsi gbe onjẹ lọ si ibẹ, awọn oṣiṣẹ si bẹrẹsi ba wọn ra onjẹ titi di ipari oṣu.

Nigbati ọkunrin yi mọ pe oṣu fẹrẹ pari, o sa kuro ni ilu! Awọn Ọlọpa si wa a titi nwọn fi ri mu. Lẹhin na nwọn si fi si ẹwọn. Bayi ni ọkunrin yi jẹ o w o awọn oṣiṣẹ wọnyi gun, ti awọn ọlọpa ko si ri owo gba pada mọ.

N. B. *Iwọ ti nka iwe yi, fi eyi kọgbọn ki o si ri idi ohun ti o ba fẹ ṣe daradara ki o ba maa da bi iṣẹ Samuel Alaṣe-igbowo, nitori gbogbo ohun ti ndan kọ ni wura.*


Advert. 134

## NOTICE

***NIGERIAN HONOURS, DECORATIONS AND AWARDS***

The National Committee on the award of Nigerian Honour would welcome suggestions from the general public on the following questions:-

(i) Do you consider that there should be only one set of National Awards, or do you consider that there should also be Regional Awards either for services rendered to the Regions or in recognition of visiting foreing dignitaries?

(ii) Do you consider that such awards should take the form of:-
(a) titles, which qualify recipients to use letters after their names, or
(b) decorations, which qualify recipients to wear medals on ceremonial occasions, or
(c) both, or
(d) neither ?

(iii) Do you consider that Foreign Honours should be accepted by Nigerians, with or without the approval of the Federal Government ?

2. Please address all communications to:-
*The Secretary,*
National Committee on Nigerian Honours,
c/o Cabinet Office,
LAGOS.

3. It will be appreciated if your suggestions are forwarded to the Secretary not later than 30th of September, 1962.

# YẸ IRAWỌ RẸ WO

ARIES (Mar 20 - Apl 21) Ẹgbẹ buruku a ma ba iwa rere ẹni jẹ. Ṣọra nipa awọn Ẹgbẹ ti iwọ yio ba rin lọsẹ yi.

TAURUS (Apl 22 - May 22) Ṣe gbogbo ere ti o ba wu o lọsẹ yi, ṣugbọn maṣe sere koja ala.

GEMINI (May 23 - June 22) Iwọ yio jẹ igbadun lario awọn Ẹgbẹ on ọgba rẹ lọsẹ yi.

CANCER (June 23 - July 23) Ṣọra rẹ lọsẹ yi, ọsẹ na yio le fun ọ, ṣugbọn ki o fi okan balẹ, ṣugbọn ki o ṣakiyesi nkan ti iwọ yio ma fi ẹmọ re jẹ.

LEO (June 24 - Aug 23) Ire ni fun ọ lọsẹ yi, gbogbo ohun ti o ngbero lati ṣe ni Ọlọrun yio r a n ọ lọwọ rẹ.

VIRGO (Aug 24 - Sept 21) Ṣe suru ninu o h u n gbogbo, ki o si ma ro ori daada ki o to ṣe nkan.

LIBRA (Sept 22 - Oct 23) Bi o ti wu ki o ri, iwọ ko gbodo ja, tabi ki o ba ẹnikan ṣe gbolohun asọ.

SCORPIO (Oct 24 - Nov 22) Meji meji ni arisiki rẹ lọsẹ yi, bi ko ja si buruku yio jasi rere.

SAGITTARIUS (Nov 23 - Dec 21) Orọ inawo nla rẹpẹtẹ kan nbọ wa ṣẹlẹ si ọ ninu ọsẹ yi.

CAPRICORN (Dec 22 - Jan 20) Iṣọra mbẹ fun ọ lọsẹ yi, maṣe ba ẹnikan ṣe ariyanjiyan ohun kan.

AQUARIUS (Jan 21 - Feb 19) Bi o ba fẹ ṣe ohun kan, ṣe itanti pe ohun mbẹ nilẹ fun.

PICES (Feb 20 - Mar 19) Ṣọra rẹ pupọ lọsẹ yi lati ma ṣe nkan pẹlu suru bi bẹkọ, nkan na ko ni gun rege-rege.

## Awọn Onisowo Niger Motor da ẹgbẹ kan silẹ

Awọn ẹgbẹ Onisowo ọrọ Mọto ti a npe ni (Niger Motors Ltd.) da ẹgbẹ kan silẹ ti nwọn npe ni (Nigeria Bedford Drivers Club)

Ohun ti a titori rẹ da ẹgbẹ na silẹ fun ni wipe ki nwọn ma fi han awọn Dẹrẹba Mọto yoku awọn lo mọ mọto wa ju, ti nwọn fi nṣe jamba.

Ẹnikẹni ti o ba nwa mọto Bedford lo ni ẹtọ lati wọ inu ẹgbẹ ti a nwi yi nibikibi ti o ba wa nilẹ Naijiria.

GBANGBA DẸKUN KEDERE BẸ WO!

## OLUBORI EGBOGI IKỌ THIOLYPTINE

Bi amodi "IKỌ" ti ọjọ re ti pẹ tabi ti o nyọ ẹ lẹnu, fun nkan bi ọdun kan tabi ju bẹ lọ, awọn egbogi rọbi rọbi ko le ṣe iwosan rẹ rara, maṣe fi owo rẹ s'ofo mọ.

Bere fun egbogi awọn ara ilu Faranse ti nwọn npe ni "THIOLYPTINE" Ojulowo haun haun atamatase egbogi fun IKỌ FERE, Ikọ Tulu, Ikọ-ọna-ọfun, Ikọ iile, Ikọ ti o ma nmu ki ẹnia ma a tu kẹlẹbẹ nigbakugba lati inu ifun wa (LUNGS) tabi ti o ma a nmu ki ẹnia ru pẹlu.

Bi o ba dan igo kan egbogi Thiolyptine wo, Iwọ na yio ri iyatọ lara rẹ ni kiakia. Igba-aya tabi ọna-ọfun rẹ ti o ma nho yio duro "IKỌ" rẹ yio si san patapata iwọ yio si ma a jẹun daradara, iwọ yio si ma sun fọnfọn pẹlu, alafia yio si de si ara rẹ.

Bere egbogi yi ati awọn oriṣiriṣi egbogi IKỌ miran ni Ṣọbu awọn:-

ADEDUN CHEMISTS
4, WAKEMAN STREET, YABA. PHONE: 22878

**Waterloo Medicine Stores**
**Palm church Street, Lagos P. O. Box 333, Lagos**
**Phone: 22878 Nigerian,** (Oja ita Faji)

NIGERIAN MEDICINE STORES
4, TINUBU STREET, LAGOS. PHONE: 20278.

WATERLOO MEDICINE STORES
11A FAGBEWESA STREET ,OSHOGBO

# IWI ASIKO

## OTITỌ PẸLU EKE

ORIN:-
(Agilinti lo mu o
(Okun tẹ dẹ faparo o
(Agilinti lo mu.
Kọlọgbọn fẹti silẹ sọrọ mi
Komọran tẹrikodo sede
Nitori bi owe bi owe
Lanlu ilu ogidi igbo
Ọlọgbọn lo njo o
Ọmọran ni i mọ ọ
Otọ dọja o kuta, owolọwọ la nreke
O tọ to sakukọ donjẹ Kọlọkọlọ
Onlo sọ babalawo oke ọhun
Dẹni nwọn nwẹnu si lara
Bi otọ ba pọ ju a solotọ di didinrin
Biruru pọ a sobmrin dẹlẹiyẹ
Ọjọ otọ ateke ja ni ibuba adan
Ni mo ti mọ wahala tinu rẹ nko ba ni
Ibẹrẹ eke bi awusa ni nri
Bo ba dalẹ a koro lẹnu ẹni
Iwaju eke ko ṣe gbe, ẹhin

*Lati Ọwọ*
*AFỌLABI OJẸLABI*

eke ewu
Ntori onibekebeke leke ibidun
Atanni sija ẹkun fọfa siṣẹ sapo ẹni
Eke ko para wọn lorukọ
Gbogbo ẹni ngbadura adun lọjọ alẹ
Ni nba otọ sọrẹ lawujọ
Otọ inu bi ẹni jẹ ewuro
Agabagebe bi ẹni jawusa
Otọ ki i ṣina, irọ ni ifori bogbe
Lọjọkọjọ otọ ni yio leke lawujọ
Otọ inu lo kan Jesu magbelebu
Otọ inu lo mu Jesu d'Oluwa wa
Eke ọdalẹ fọ Judasi dọrẹ apania
O gbowo ina, o dolowo ntori ibi
Igbẹhin eke, ṣe bi i ti Judasi lo nri
Igbẹhin ọdalẹ ki i sunwọn lawujọ
Ọjọ otọ pẹlu eke pade ija Ọkanjuwa on ilara nran eke lọwọ
Awọn afomọ adugbo ko mọ atiṣe
Adan nlo sọtun sosi ntori owo
Otọ gborukọ lori, o nwọju Oluwa
Otọ ni Ilara pẹlu Ọkanjuwa ku aigbọn
Ṣe bi aṣe he ada loko igbo
Bẹ ni yio ṣe nu lọdan o jare
Ọrẹ eke ko layọle rara
Alayonbẹrẹ loni bekebeke
Ṣugbọn bi alabala pegba nita
Ki paraka pegbeje nigbalẹ
Ologbojo ni baba egungun
Bilara so pọ mọkanjuwa
Leke tori owo gbagbe ati sun
Oju-oro ni leke omi,
Osibata ni leke odo
Otọ inu a bori eke lawujọ

ORIN:-
(Agilinti lo mu o
(Okun tẹdẹ faparo o
(Agilinti lo mu

## Olotu Onisowo U. A. C. nrele

Oyinbo ti a nwo aworan rẹ ninu iwe yi ti orukọ rẹ njẹ Ọgbẹni M. C. Walker, ti o wọ iṣẹ labẹ wọn lọdun 1953, gẹgẹbi Olotu ile-iṣẹ iṣowo na (Personnal Manager) gba isimi patapata kuro lẹnu iṣẹ.



*ỌGBẸNI M. C. WALKER*

Lati ibi iṣẹ (Anglo Iranian Oil Company) ni Oyinbo yi ti wa wọ iṣẹ U. A. C. lọdun 1952. On lo ntọju awọn oṣiṣẹ ni ebute Burutu, Port harcourt ati ni Kano. Lati ibẹ lo ti wa gba oye ipo pataki ni Eko, gẹgẹbi Olutọju awọn Oṣiṣẹ (Labour Officer) Ọjọ ori rẹ to ọdun mejidiladọta.

Ọgbẹni I. B. Mendel ni yio gba ipo rẹ. O dabọ o.

## ỌDARAN KAN KU S'ẸWỌN

SAPẸLẸ:- Idaamu nla ba gbogbo awọn ẹlẹwọn ninu ọgba wọn nigbati Ọdaran kan, George Okotie ẹni ọdun merindinlogbọn jẹun owurọ tan ti o si ku bamubamu, ni ọjọbọ ti iṣe ọgbọnlọ oṣu yi.

Lẹsẹkẹsẹ ni gbogbo awọn ẹlẹwọn pejọ ti nwọn si nwo. Ni awọn ẹlẹwọn ba ta panpa, nwọn si pinnu wipe awọn ko ni jẹun, awọn ko si ni mu omi, bẹni nwọn si kọ lati lọ ṣe iṣẹ wọn ni ode.

Awọn ọga oṣiṣẹ awọn ẹlẹwọn si bẹrẹsi bẹ wọn lati jẹun.

# EYI NI AWON OJO OJA ILE YORUBA

## OJO AJE SEPTEMBER 10 (MONDAY)

| ILU | ORUKO AWON OJA |
|---|---|
| EKO ATI AGBEGBE RE ABEOKUTA | Ọbun - Eko, Ojuwoye Atan, Agbado, Ifọ, Itori, Itoku Isabọ, Odeda, Ibara |
| IBADAN | Fẹdẹgbo, Oyedeji, Ẹgbẹda, Babalokuta |
| IJEBU | Ilishan, Odogbolu, Atan, Imope Isara, Imodi, Ishan |
| IJESHA | Ẹpẹ, Iloba, Imuroko, Erinmọ Ilase, Iperindo |
| ẸGBADO | Aiyetoro, Ado - Odo |
| EKITI | Egosi, Odo—Aiyedun |

## OJO ISEGUN SEPTEMBER 11 (TUESDAY)

| ILU | ORUKO AWON OJA |
|---|---|
| EKO ATI AGBEGBE RE ABEOKUTA | Mushin Otta, Abalabi, Sodẹkẹ, Omida, Ilawọ |
| IBADAN | Ituko, Sojukonko, Towọbowọ, Temidire |
| IJEBU | Ikẹnnẹ, Ọkun - Ọwa, Erunwọn, Omu, Mamu |
| IJESHA ẸGBADO | Oshu, Ifagun, Odogbo, Idoko, Iloko |
| EKITI | Igbogila, Ijoun, Imasai, Owode Oke—Aiyedun, Ikọle |

## OJO'RU SEPTEMBER 12 (WEDNESDAY)

| ILU | ORUKO AWON OJA |
|---|---|
| EKO ATI AGBEGBE RE ABEOKUTA | Agege, Ikeja Lafenwa, Ọbada, Ọba, Kajọla, Ajegunle, Idogo |
| IBADAN | Lalupon, Ajegunle, Owode, Igbo-ọra |
| IJEBU | Ibẹfun, Atikori, Imushin, Agọ-Iwoye, Ijesha, Ijebu, Isara Imodi |
| IJESHA | Iwara, Ejioro, Odo, Ibokun Ijebu,-Ijesha |
| ẸGBADO | Lasilo, Idiẹmi |
| EKITI | Okemesi, Ifaki |

## OJO OJOBO SEPTEMBER 13 (THURSDAY)

| ILU | ORUKO AWON OJA |
|---|---|
| EKO ATI AGBEGBE RE ABEOKUTA IBADAN | Oyingbo Ijoko, Ibẹrẹkodo, Asu, Wasimi Akeroro, Idofin, Lagun, Ṣagbẹ, Ogunjana, Molete |
| IJEBU | Aiyepe, Ṣagamu, Ilaosu, Ogere, Irolu, Itele, Ode - Remọ |
| IJESHA ẸGBADO | Ibodi, Ibode, Kajola, Imesi - Ile Alagba, Ilarọ, Oja—Ọdan, Sunwa, Iboro |
| EKITI | Ilogbo, Ishan |

## OJO ETI SEPTEMBER 14 (FRIDAY)

| ILU | ORUKO AWON OJA |
|---|---|
| EKO ATI AGBEGBE RE . ABEOKUTA | Ọbun-Eko, Ojuwoye, Ikosi, Ẹpẹ Atan, Agbado, Ifọ, Itori, Itoku, Isabọ, Odeda, Ibara |
| IBADAN | Fẹdẹgbo, Oyedeji, Ogbaro, Ẹgbẹda, Babalokuta |
| IJEBU | Ilishan, Odogbolu, Atan, Imope, Ishan, Isara, Imodi |
| IJESHA | Ẹpẹ, Iloba, Imuroko, Erinmọ, Ilase, Iperindo |
| ẸGBADO | Aiyetoro, Ado - Odo |
| EKITI | Egosi, Odo - Aiyedun |

## OJO ABAMETA SEPTEMBER 15 (SATURDAY)

| ILU | ORUKO AWON OJA |
|---|---|
| EKO ATI AGBEGBE RE . ABEOKUTA | Mushin, Badagry Otta, Abalabi, Sodẹkẹ, Omida, Ilawọ |
| IBADAN | Ituko, Sojukonko, Towọbowọ, Temidire |
| IJEBU | Ikẹnnẹ, Ọkun-Ọwa, Erunwa Omu, Mamu |
| IJESHA | Oshu, Ifagun, Odogbo, Idoko, Iloko |
| ẸGBADO EKITI | Igbogila, Ijoun, Imasai, Owode Oke—Aiyedun, Ikọle |

## OJO AIKU SEPTEMBER 16 (SUNDAY)

| ILU | ORUKO AWON ILU |
|---|---|
| EKO ATI AGBEGBE RE . ABEOKUTA | Ikẹja, Agege, Ebute-Ero, Ọjọ Ajido Lafenwa, Ọbada, Ọba, Kajọla, Ajegunle, Idogo |
| IBADAN | Lalupon, Ajegunle, Owode, Igbo-ọra |
| IJEBU | Ibẹfun, Atikori, Imushin, Agọ-Iwoye, Ijesha-Ijebu, Isara, Imodi |
| IJESHA | Iwara, Ejioro, Odo, Ibokun, Ijebu-Ijesha |
| ẸGBADO EKITI | Lasilo, Idiẹmi Okemesi, Ifaki |

## OJO AJE SEPTEMBER 17 (MONDAY)

| ILU | ORUKO AWON OJA |
|---|---|
| EKO ATI AGBEGBE RE . ABEOKUTA IBADAN | Oyingbo, Ejinrin Ijoko, Ibẹrẹkodo, Asu, Wasimi Akeroro, Idofin, Lagun, Ṣagbẹ, Ogunjana, Molete |
| IJEBU | Aiyepe, Ṣagamu, Ilaosu, Ogere Irolu, Itele, Ode - Remọ |
| IJESHA ẸGBADO | Ibodi, Ibode, Kajola, Imesi - Ile Alagba, Ilarọ, Oja - Ọdan, Sunwa, Iboro |
| EKITI | Ilogbo, Ishan |

# IROHIN KAKIRI AGBAIYE

*CAIRO:—*

Ariwo ta ge e, nigbati Reluwe kan sọ kalẹ lori irin ti o si wọ ile gbe ọkunrin kan ti o sun nigbati ọkunrin na taji loju orun o ba on ati bẹdi rẹ l'oke Reluwe ṣugbọn ko f'ara pa!

*ROMU:—*

Gbogbo awọn Dokita ni nwọn da iṣẹ silẹ ninu ọsẹ ti o kọja nitori ipe nwọn fẹ ọkunwo ati awọn nka idagbasoke miran.

*NYASALND:—*

Dokita Hactingo Banda, Minista ohun isura ilẹ ati alamojuto ẹto Ijọba ti ṣe kilọki'ọ fun gbogbo enia lati dẹkun owo fi si ile Ifiwe ranṣẹ-

*KATISINA:—*

Awọn Ọlọpa ti ri Ogun Baisikulu ti o ti nsọnu kakiri Naijiria, nwọn si ti mu awọn enia mẹrin ti nwọn nji Baisikulu kakiri.

*HONG-KONG:—*

Adọta (50) enia lo ku bamubamu igba (200) enia lo fi ara pa, ẹdẹgbajọ (15,000) enia ni o si di alainile mọ nigbati afẹfẹ nla kan fẹ, ti o si da gbogbo ilu ru. Nwọn si tun nwa awọn enia mẹtala lọwọ nisisiyi ti nwọn ko mọ bi nwọn ku tabi nwọn ye ni.

*ONITSHA:—*

Ọgbẹni Chukume ti iyawo rẹ Cecilia sa kuro nilẹ ni ọjọ kẹsan ti o bimọ titun ni Ibadan ri iyawo rẹ na lọdọ awọn Obi rẹ lẹhin ọjọ mẹsan ti o ti nwa. Ṣugbọn awọn obi iyawo rẹ ko jẹ ki iyawo rẹ o pade si ọdọ ọkọ rẹ ni Ibadan.

*KAMUNGONO:—*

Ọjọ gbogbo ni t'ole ọ/ọ kan ni to lohun. Awọn Ọkunrin meji kan ni Ogun (20) enia lu pa bamubamu nigbati nwọn lọ /i agutan gbe. Ọwọ Palaba segi!

*EMEKUKU:—*

Ọmọ ile-iwe kan Paul Ike ni Aja buje bi o ti nlọ si Ṣọọṣi, lẹsẹkẹsẹ ni nwọn gbe e lọ si ile-iwosan Owerri. Bi Padi Ṣọọṣi na ti fẹ gbadura fun un, ni o ba gẹ e jẹ, Ọmọ na si ku, ipa ni nwọn fi yọ ọwọ Padi lẹnu rẹ.

*EKO:—*

Awọn Alaṣẹ Ọkọ oju Omi (Ports Authority) ti ṣe ipinu lati da adọtalerugba (250) awọn Oṣiṣẹ silẹ nitori eto ẹsunna owo

*BAMAKO*

Ọgbẹni Modibo Keita, Alakoso Ijọba Mali pada si Bamako lẹhin ibẹwo rẹ si ilu Ivory Coast ninu Ọsẹ ti o koja yi

*MUSHIN*

Awọn ẹgbẹ awamọto (Nigeria Motor Drivers Union ati Allied Transport Workers) ti da ile iwe awamọto kan silẹ ni Ọlorun-ọgo lati ma'a kọ awọn awamọto ni ofin ki ijamba oju ọna le ba dinku.

*ABEOKUTA:—*

Ọkunrin kan ti Iyawo rẹ ku ni on na ba lọ si oti kereni Odo Oogun o si bẹ sinu Odo-Oogun. O ni on fẹ ba olufẹ on ku, ṣugbọn awọn enia tete yọ Ọkunrin na jade.

*KENYA:—*

Enia mẹsan ni awọn Ọlọpa yinbọn pa nigbati ija igboro kan ṣẹlẹ ninu ọsẹ yi ni agbegbe kan ti nwọn pe ni Liwani.

*IJEBU-ODE:—*

Ọgbẹni D. S. Ajagbala ti ṣe ileri pe, on yio fun ẹniti o ba ba on ri Iyawo on ni pọnun marun sile marun (£5 : 5/-)

Iyawo rẹ Muyidatu loyun o si dagbere pe on nlọ si Ile itọju awọn aboyun, ṣugbọn nlọ rẹ ni nwọn ri, nwọn ko ri abọ rẹ.

## KERE O! AKIYESI PATAKI

Awa sa le jeri wipe Ojulowo bayanbayan Egbogi gidi ni LEOPILLS, awa ta nlo ni Gold Coast (Ankara) Ghana pelu, mejiri re ko si nitu gbogbo orisirisi Egbogi kakiri Ilu Nageria.




### Irohin kakiri Igboro Ilu Eko

Ile na ni owo ni igboro Ilu Eko, Irohin ti o wa lenu gbogbo enia lomode Lagba ni asiko yi ti nwon si fi se oro ati orin laarin ara won ni nipa Egbogi Jamani olokiki yi ti nwon npe ni LEOPILLS.

Imoran awon Dokita Oyinbo ti nwon npe iwadi Egbogi LEOPILLS, ni kan so wipe bi o ti lagbara to, ti o je Ojulowo giriki ati alamatase fun iwosan "JEDIJEDI" bi o ti wu ki o/o re pe to lenu ni awon le tun fi owo s.ya tabi se ileri fun gbogbo awon ti amodi tabi, Igbe ise tabi aiko ri igbonse deede, Ion tirun nibgakugba, ara riro Ehanri, Ehin didun, Oju sisan, tabi aiko riran kedere kokoro buruku lara, Ori inu Onigbameji ati orisirisi arun miran gbogbo pelu "Wipe" nwon yio ri alafia ni kiakia ti nwon ba nlo Egbogi LEOPILLS nitorpe a si fun ma fun eje se lara enia nipa siso di oun pitapata.

SE IRANTI PE ALAFIA L'OGUN ORO, IJAFARA SI LEWU PELU (POSTAGE 1/9d)

**IYE OWO EGBOGI LEOPILLS:-** Igo nla sile mefa abo (6/6d) pere ni, Igo kekere sile meta abo (3/6d) pere ni.

Bere Ojulowo Egbogi omiran fun orisirisi Amodi ti o ba fere ni Sobu awon:—

**Waterloo Medicine Stores**
8, Palm Church Street, P. O. Box. 333. Lagos Nigeria. Phone 22878, ati pelu ni Sobu awon arabinrin Mrs. C. O. Babajide near Health office Ibadan ati ni Abimbola Medicine Store B29 Okesha Street Ilesha. Bisale Medicine Stores, British & Forege Medicine (Dealer) S. W. 6/458 AGBOKOJO STREET, IBADAN N.

AKIYESI:- Ri daju gbamgba wipe Sobu ti nwon nta lo gbe ranse lo ra, bi be ko awon elomiran yio fi ERU lo ta Adamodi tabi orisirisi omiran fun o o, mase gba rara.

# KERE O! KERE O!!

## CORPULENSE FAT REDUCING TABLETS

A se iwadi egbogi yi fun oyin enia wa ti o lomi lara lokunrin ati lobinrin lomode ati lagba ni Ile Naijiria oguo ara sisan ni wa lati iwo orun Jamani, Ajebidan logun yi, lo o wo logan ni ara re yio fuye ara sisan ko ye o iwo omolokunrin ati omolobinrin arun buburu ni bi enia ba sanra pupoju, ara sisan ju yio mu o darugbo lojiji.

Ara sisan ju yio mu o wuwo leri irin.

Ara sisan ju yio mu o buru ewa, ara sisan ju yio mu ki omobinrin mase tete loyun, ara sisan ju yio mu are ara fun iwo omolokunrin ati le sunmo obinrin.

Tete ra egbogi yi fun ilo re ni kiakia.

Bere lowo onisegun adugbo re tabi ni odo awon ojogbon Onisegun:-

(1) Champion Chemist 25, Agoro Street, Lagos.
(2) Gem Medicine Stores Tokunboh Street, Lagos.
(3) Cosmopolitan Chemists Strachan Street, E.B
(4) West African Chemists 35, Agarawu Street, Lagos.
(5) New Era Chemists 77, Azikiwe Street Lagos.

HASSAN COMMERCIAL MEDICINE STORES
26, Bishop Street. Lagos. Phone:- 23745 Lagos.


## Nigerian Ports Authority

### INVITATION TO TENDER

### CONTRACT FOR SUPPLY OF LABOUR FOR
### (a) "C" WAREHOUSE, APAPA QUAY
### (b) "D" WAREHOUSE, APAPA QUAY

The Nigerian Ports Authority invite tenders from Contractors to supply experienced labour with adequate supervision for the handling of cargo at "C" and "D" Warehouses, Apapa Quay.

2. Tenders which must be submitted on forms provided by the Authority for each Warehouse separately and returned in sealed envelopes marked "CONFIDENTIAL-TENDER FOR LABOUR "C" (or "D" as thecase may be) WAREHOUSE" should be addressed to the Secretary to the Authority, Nigerian Ports Authority, 216, Broad Street, Lagos, so as to reach him not later than 4 o'clock in the afternoon of Monday, 17th September, 1962.

3. Tenderers may tender for either one or both of the two Warehouses.

4. Persons tendering for "C" Warehouse must use the Form of Tender bearing "C" Warehouse and persons tendering for "D" Warehouse must use the Form of Tender bearing "D" Warehouse.

5. The issue of an official form of tender will be subject to a deposit of £10 for each warehouse, payable to the Authority's Cashier, Accounts Department, Apapa Quay. The deposit will be returned on receipt of bona fide tender.

6. Only applications from labour contractors who have had experience in similar work will be considered, and the Authority do not bind themselves to accept the lowest or any tender.

7. Applicants wishing to view either "C" or "D" Warehouse or both before submitting tenders should apply in person to Chief Traffic and Commercial Manager, Apapa Quay.

*BAYO KEHINDE*
*Secretary to the Authority*

N. P. A. Notice No. 761
30th August, 1962.


BERE EGBOGI PATAKI YI TI NWON NPE NI:-

# "Figurana"

Je ojulowo egbogi ti awon Jamani sese se iwadi re fun awon ti o ba sanra tabi ti o ba "TOBI" ju lati ma mu ki nwon le fon tabi jonku lai si wipe nwon ma ka ewo onje ti nwon o ma je rara be si ni ko lewu ni lilo fun enia rara.

Ki enia sanra, gbotin, tabi ki o tobi pupoju ki nse ohun ti o dara, rara, opolopo amodi ni o nko ba enia, bi Lakuregbe, Aikole gbere ni ile bi o ba joko Aya lilu kiki tabi jija nigbakugba aikole mi kanle daradara, ara wiwo tabi wiwuwo, Eemi mimi ho-ho ati orisirisi amodi omiran pelu.

Sa dan Igo re kan wo, Iwo na yio ri ayipada ati Alafia ti yio de si o. Bere ni Sobu awon Olori elegbogi Jamani ni igboro ilu Eko:-

ADEDUN CHEMISTS
4, WAKEMAN STREET, YABA PHONE: 22878

**Waterloo Medicine Stores**
**Palm church Street, Lagos P. O. Box 333, Lagos**
**Phone: 22878 Nigerian,** (Oja ita Faji)

NIGERIAN MEDICINE STORES
4, TINUBU STREET, LAGOS. PHONE: 20278.

WATERLOO MEDICINE STORES
11A' FAGBEWESA STREET ,OSHOGBO


*Printed and Published by MODUPE PRITING PRESS*
*16, Bamgbose Street P. O. Box 1495, Phone 21985, Lagos*
*Olotu:— E. A. Adeniji. 24, Olujide, Street Odo—Abore Mushin*